# Bibeli fun awon omode

# Ajinde akoko




Ikosile gba owo: Edward Hughes

Atunmo ede: Oluwashina Oluwadimu

Ayaworan: Janie Forest

Olu'lo: Lyn Doerksen


Itan 54 ti 60


**www.M1914.org**

***Bible for Children,*** *PO Box 3, Winnipeg, MB R3C 2G1 Canada*



Iwe ase: Oni ase lati se atunko tabi attune itan yi, niwon igba ti o ko so di owo.


Èdè Yorùbá

Yoruba








Rara o! Olorun se dada. Jesu ko se asise. Jesu mo wipe a o pa ohun gba owo awon eni ibi. Nigbati Jesu wa ni omode, Simeoni arugbo ti so fun Maria ohun ibi to nbo wa sele.

3



Ojo die ki ato pa Jesu, arabinrin kan wa lati wa da ororo iyebiye si ese Jesu. "O n da owo nu" awon omo ehin re wi. "Oti se ise rere" Jesu wi bayi. "O se eyi fun isinku mi". Iru oro kayefi wo re!

4

Lehin eyi, Judasi, okan ninu omo ehin mejila, gba lati fi Jesu han fun awon alufa agba pelu ogbon wura.



5



Li ajo irekoja awon Ju, Jesu je ounje igbehin pelu awon omo ehin re. o so ohun iyanu fun won nipa Olorun ati awon ileri re si awon to feran re.

6



Jesu si fi akara ati omi fun won lati pin. Eyi ni lati ran won leti wipe Jesu fi ara ati eje re fun wa fun idariji ese.

7

Jesu si so fun awon omo ehin re wipe a o fi ohun han awon omo ehin re yio si fonka. "Emi ko ni salo", Peteru wi bayi. "Ki akuko to ke, iwo yio komi sile leemeta," Jesu wi.



8


Li oru ojo na, Jesu lo lati gbadura ninu ogba Getsimani. Awon omo ehin re ti owa lodo re sun lo fonfon. "Baba a mi", Jesu gbadura, "… Jeki ago yi re koja lori mi, sugbon kiise bi mo tife, Ife re ni ko se."
9


Lojiji, opo ero wonu ogba, Judasi lo siwaju won. Jesu ko ja, sugbon Peteru ge eti okunrin kan sile. Lai pariwo, Jesu fi owo kan eti arakunrin na osi wo san. Jesu mo wipe ki amu ohun pelu ife olorun fun ohun.
10


Awon eyi mu Jesu lo si ile Alufa agba. Nibe, awon agba Ju so wipe ki Jesu ku. Nitosi, Peteru duro leba ina awon eru osi nworan.
11


Leemeta li awon eniyan wo Peteru won si wipe "Iwo wa pelu Jesu!" Leemeta Peteru ko eyi, gegbi Jesu se wi. Peteru gegun o si bura.
12


KUKURUKUUUU!
Gele, akuko ke. O dabi ohun Olorun si Peteru. O ranti oro Jesu, Peteru sonkun kikoro.
13


Judasi pelu bara je. O mo wipe Jesu ko jebi ese Kankan.
14


Judasi gbe ogbon wura pada sugbon awon alufa ki yio gba. Judasi so owo na sile, o jade lo – o si pokun so.
15
Awon alufa mu Jesu to Pilatu wa, Gomina Romu. Pilatu so wipe, "Emi ko ri ese kan pelu okunrin yi." Sugbon awon eniyan gbogbo wipe, "Kan mo agbelebu! Kan mo agbelebu!"
16
Nigbeyin, Pilatu gbo, osi pase ki akan Jesu mo igi agbelebu. Awon Omo-ogun gba Jesu lese, tu ito si loju, won si naa legba. Won de ade egun lee lori. Won si kan mo igi agbelebu lati ku.
17
Jesu mo wipe ohun yio ku iku oro yi. O si mo wipe iku re yio mu idariji ese wa fun awon to gbekele ohun. Ole meji li akan pelu Jesu. Okan gbagbo – o losi paradise. Ekeji ko gbagbo.
18
Lehin ijiya pipe, Jesu wipe "o ti pari," o si ku. Ise re ti pari. Awon ore re sin sinu isa oku titun.
19
Awon omo-ogun Romu so ibi iboji. Kosi eniti o le wole - tabi jade.
20












Laipe, Jesu pada waba awon omo ehin re, o si fi owo re han won. Otito ni. JESU WA LAAYE SI! O DARIJI Peteru ti o ko sile, o si wi fun awon omo ehin re ki won so fun gbogbo eniyan nipa ohun. O si pada losi orun ti oti wa nigba keresimesi akoko.

24

Ajinde akoko

Itan lati inu oro Olorun, Bibeli

lari ka ninu

Iwe Matthew 26-28, Luku 22-24, Johannu 13-21

"Iwole oro re funwa ni imole."
Orin Dafidi 119:130

Olorun mo wipe ati se ohun ibi, ti ope ni ese. Iku ni ere ese.

Olorun feran wa tobe ge tofi omo re kan soso, Jesu, ranse lati ku lori igi agbelebu ki osi jiya fun ese re. Jesu si pada wa si aaye osi losi ile l'orun! Nisiyi Olorun le dari ese jiwa.

Bi o ba fe yi pada kuro ninu ese re, so fun Olorun bayi wipe: Olorun mi owon, Mo gbagbo wipe Jesu ku fun mi osi ye. Jowo wa sinu aye mi ki o si dari ese mi jimi, ki emi bale ni aye otun nisisiyi, kiisi ba o gbe titi lailai. Ranmilowo lati gbe igbe aye mi fun o gegebi omo re. Amin. Johannu ori keta ese kerindinlogun.

Ka Bibeli re ki osi ba Olorun soro lojumo!